# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

**OSÙ KEJE, ỌDÚN 2023**

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**Ìsìn Omi Iná**

**Oṣù Keje, Ọdun 2023 – Ìsìn Omi Iná**

**<u>ÀWỌN ORIN ÌBẸ̀Ẹ̀RẸ̀</u>**

**Ègbè**

Ohun gbogbo n tàn, ó lẹ́wà
Ẹ̀dá nlá, kékeré
Ohun gbogbo gbọ́n, ó nyanu
Ọlọ́run dá gbogbo wọn.

1. Tànná kékeré tó ṣí,
Ẹyẹ bíntín tó n kọrin,
Ó dá àwọ̀ dídán wọn,
Ìyẹ́ wọn tíntínní.

2. Òkè èsè àlùkò,
Odò tí n ṣàn lọ,
Ìrọ̀lẹ́, at'òwúrọ̀,
T'ó n mófurúfú tán.

3. Ìjì tútù n'nú ọyẹ́,
Òrùn ìgbà ẹ̀rùn,
Èso pípọ́n ní ọgbà,
Ó dá wọn lọ́kọ̀ọ̀kan.

4. Ó fojú fún wa láti rí,
Àt'ètè ka lè sọ,
B'Élédùmarè ti tóbi tó,
Tó móhun gbogbo dára.

1. **Ọlọ́run t'Ó mú Ísráẹ́lì la òkun já.**
Tí Ó sì gbà wọ́n kúrò lí oko ẹrú,
Tí Ó rọ̀'jò ónjẹ sílẹ̀ láti ọ̀run,

Òn ni mo ngbàdúrà sí.

Ègbè
Ọ̀kan ná lónì, ọ̀kan ná lónì,
B'ákokò tí Ó sin Ísráẹ́lì la òkun;
Ọmọ Rẹ̀ ní un ó jẹ̀, 'torí ọ̀rọ̀ Rẹ́ sọ
Pé, ọ̀kan ná nì Ọlọ́run
Ìyanu lónì.

2. Ọlọ́run t'Ó gba Dáníẹ́lì lọ́wọ́ Kinìún,
T'Ó sì yọ àwọn mẹ́ta n'nú iná'léru,
Ẹni tí àwọn ìràwọ̀ ngbà Tirẹ̀ gbọ́,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

3. Ọlọ́run t'Ó f'ọ̀rọ̀ Rẹ̀ d'áfẹ́fẹ́ dúró,
T'Ó sì nsọ 'bànújẹ́ òní d'ayọ̀ lọ́la,
Ẹni tí Ó yí òkúta 'bojì kúrò,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

4. Ọlọ́run t'Ó wọ itànná ìgbẹ́ l'áṣọ,
Ẹni t'Ó mú omi ṣàn n'íyàngbẹ ilẹ̀,
Tí Ó wẹ ẹlẹ́ṣẹ̀ mọ́ nínú èrí rẹ,
Òn ni mo ngbàdúrà sí.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Bàbá mi àti Ọlọ́run mi, bí n ó ṣe képè orúkọ Olúwa lónì, jẹ́ kí ìtúsílẹ̀ wá sórí ayé mi, kí ibànújẹ́ ayérayé wá sórí àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
2. Gbogbo ahọ́n tí wọ́n yàn láti dìde lòdì sí ìgbésókè mi láyé, gba ìdájọ́ iná atòkèwá báyìí, ní orúkọ Jésù.
3. Ọlọ́run, nínú ètò tòní, dìde nínú àrá agbára Rẹ, kí O sì túká àwọn ọ̀tá olóríkunkun tó takú pé òun kòní jẹ́ kí ayànmọ́ mi lọ, ní orúkọ Jésù.

4. Gbogbo aninilára tó n tẹrí ayé mi ba, ilẹ̀ isìnkú rẹ rè é, kú nípa iná báyìí, ní orúkọ Jésù.
5. Olúwa, jẹ́ kí àwọn òkò àdúrà mi níyìn lónì, ṣàwárí iwájú orí ọ̀tá mi, kí ó sì pa á run, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo agbára tó n fọ́nnu lòdì sí mi, idà iná yóò yà ọ́ lárọ lónì, ní orúkọ Jésù.
7. Ìrúnú àti ìbínú Ọlọ́run, ṣàwárí Fáráò ilé bàbá mi lónì, kí o sì pa á run, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ

**ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ọ̀tá mi ṣe aṣìṣe tí yóò jẹ́ kí n tẹ̀síwájú, ní orúkọ Jésù.
4. Iná Ọlọ́run, jó aṣọ ogun àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
5. Mo de gbogbo ẹ̀mí tó n kó ayídáyidà bá àwọn olóóré mi lòdì sí mi, ní orúkọ Jésù.
6. Olúwa, mú ìjákulẹ̀ bá ìgbógun tì ọ̀tá lórí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
7. Olúwa, jẹ́ kí n rí ojúrere lọ́dọ̀ àwọn tí yóò pinnu lórí ìlọsíwájú mi, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Deuterónómì 20:4:** Nítorípé OLÚWA Ọlọ́run nyín ní mbá nyín lọ, láti bá àwọn ọ̀tá nyín jà fún nyín, láti gbà nyín là.

**Rómù 8:31:** Njẹ́ kíli àwa ó ha wí sí nkan wọ̀nyí? Bí Ọlọ́run bá wà fún wa, tani yóò kọ ojú ìjà sí wa?

**Rómù 8:39:** Tàbí òkè, tàbí ọ̀gbun, tàbí ẹ̀dá míràn kan ni yóò le yà wá kúrò nínú ìfẹ́ Ọlọ́run, tí ó wà nínú Krístì Jésù Olúwa wa.

**Isàíàh 41:13:** Nítorí èmi Olúwa Ọlọ́run rẹ yóò di ọwọ́ ọ̀tún rẹ mú, èmi ó wì fún ọ pé, Má bẹ̀rù; èmi ó ràn ọ́ lọ́wọ́

**Orin Dáfídì 108:13:** Nípaṣẹ̀ Ọlọ́run li àwa ó ṣe akin; nítorí Òun ni yóò tẹ àwọn ọ̀tá wa mọ́lẹ̀.

**Lúkù 10:19:** Kíyèsi i, èmi fún nyín lí àṣẹ láti tẹ ejò àti àkékè mọ́lẹ̀, àti lórí gbogbo agbára ọ̀tá: kò sì sí ohùnkan bí ó ti wù kí ó ṣe, tí yóò pa-nyín-lára.

**Ìfihàn 12:11** Nwọ́n sì ṣẹ́gun rẹ̀ nítorí ẹ̀jẹ̀ Ọ̀dọ́-Àgùntàn ná, àti nítorí ọ̀rọ̀ ẹ̀rí wọn, nwọn kò sì fẹ́ràn ẹ̀mí wọn àní tìtí dé ikú.

.

**<u>ÀDÚRÀ SÓRÍ OMI</u>**

1. Bàbá mi, mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ fún ṣíṣẹ̀dá omi gẹ́gẹ́ bí àdìtú àrà iṣẹ̀dá Rẹ. Olúwa, Ẹ ṣeun nítorí omi jẹ́ ààmí àpẹrẹ Ẹ̀mí Mímọ́. Omi n fọ̀ nkan, ó n sọjí, tẹ́nilọ́rùn, sọdọ̀tun, mú dúró, wẹnùmọ́, ó sì tún jẹ́ amú nkan dàgbà.
2. Olúwa, dìde nípa agbára Àjínde Rẹ, kí O sì mí èmí Rẹ sórí àkójọpọ̀ omi yî. Jẹ́ kí iná Ẹ̀mí Mímọ́ ṣíji bo omi yìí, kí O sì sọ ọ́ di iwòsàn atòkèwá, omi iṣẹ̀dá, omi tó n rún ẹ̀mí òkùnkùn wómú-wómú, ajíra atòkèwá àti egbòògi aporó atòkèwá, ní orúkọ Jésù.
3. Bàbá mi, jẹ́ kí ohun gbogbo tó n bẹ nínú omi yìí gbé iná tíkò ṣe é pa, èyí tí yóò dójútì gbogbo irúgbìn òkùnkùn nínú ẹ̀jẹ̀ mi àti ní gbogbo àgọ́ ara mi pátápátá, jẹ́ kí ó pèníjà gbogbo májèlé tó farasin nínú ara mi, kí o sì tì í jáde, ní orúkọ Jésù.
4. Bàbá Olúwa, bí n ó ṣe mu omi yìí, jẹ́ kí agbára omi ìyè dàpọ̀ mọ ọ, sì jẹ́ kí ó sọ ìgbà èwe mi di ọ̀tun bí ti idì, jẹ́ kí ẹ̀mí ọgbọ́n, ẹ̀mí òye, ẹ̀mí imọ̀ràn àti ẹ̀mí ipá, ẹ̀mí ìmọ̀, àti ẹ̀mí ibẹ̀rù Olúwa bàlé ayé mi, ní orúkọ Jésù
5. Olúwa, bí n ó ṣe mu omi yìí, jẹ́ kí ó fọ gbogbo ìrúgbìn òkùnkùn kúrò nínú ayé mi, si jẹ̀ kí ó nù dànù ibànújẹ́ àti omi ìkorò tó n dàmú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
6. Agbárákágbara tó n tako ètò àti ipìnnu atòkèwá Ọlọ́run fún ayé mi, di ṣíṣí dànù nípa omi iná yìí, ní orúkọ Jésù.

7. Ọlọ́run dìde, jẹ́ kí omi yìí tú gbogbo ìwo òkùnkùn tí wọ́n gbìn lòdì sí ayé mi ká, jẹ́ kí ó pa gbogbo pẹpẹ tí wọ́n gbé kalẹ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi ní àyíká mi run, ní orúkọ Jésù.
8. Ìwọ omi yìí, wẹ aìsàn, àmódi, aìlèra àti àrùn títí dójú ikú jáde kúrò nínú ayé mi, ní orúkọ Jésù.
9. Ẹ̀yà ara tóti dòkú ìyówù nínú àgọ́ ara mi, gba ìyè nígbà tí o ba á bá omí iná yìí pàdé, ní orúkọ Jésù.
10. Bàbá, jẹ́ kí omi iná yìí tú ìwà ìkà olóríkunkun àti àjẹ́ olóríkunkun nínú àgbègbè mi ká, ní orúkọ Jésù.